A W' AIYE MA N'IGBA O DABI IGBA TI
EṢINṢIN KU SI OJU. ỌTI

# AKEDE EKO.

LATI KEDE ANU FUN AWỌN OTOṢI ATI MẸKUNU, ATI LATI GBA AWỌN OJIYA ENIA KURO LỌWỌ IDAMU AWỌN ALAGBARA

VOL. IV. No 37 SATURDAY, September 19, 1931. THREEPENCE.

NIGERIAN SECRETARIAT
12. 9. 31
LAGOS

S.C.O.A.

## SOCIETE COMMERCIALE DE L'OUEST AFRICAIN

152-156, BROAD STREET,
121, VICTORIA STREET,
144, VICTORIA STREET,
3, DENTON STREET, EBUTE-METTA.
ABẸOKUTA (IBARA ROAD).

***SELLS EVERYTHING***

**To Meet Every Body's Purse.**

Provisions
Cottons
Hardware
Drugs.

Best Quality
Lowest Prices
Quick Attendance

***Have a Trial***

AND

**You will become our regular customer.**

AWA NI ONIṢỌWỌ TI YIO FUN NYIN L'ERE PUPỌ LORI OJA

S.C.O.A.

# MESSRS: J. H. DOHERTY,

**LIMITED,**

## INVITE YOU

TO INSPECT THE LARGE RANGE OF NEW MATERIALS IN THEIR NEW BROAD STREET STORES:

## Included in which are:

Newest and Finest Shades and Designs
LADIES' DRESS MATERIALS, LADIES READY-MADE DRESSES, AND GENTLEMEN'S SUITINGS.

**Do Not Fail To See Our**

**Ladies' and Gentlemen's Hats, Shoes, Hosiery, etc.,**
Ladies Underclothing of all kinds,
Gentlemen's Shirts, Ties, and Pyjamas.

Beds, Beddings, Hardware, Cutlery Grockery, Chairs, Tables, Picture Frames Suit Cases, Fresh consignments every steamer.
Gramophone and Gramophone Records. Humber Cycles by instalments.

**COME ONE! COME ALL!!**

***Lowest Prices*** ***Highest Quality.***

P.O BOX NO. 140, LAGOS. PHONE 182, LAGOS.

# SABU "OGA NI DUHATI."

Ẹnyin Ọmọge Alafẹ, l' ọkunrin ati l' obinrin, eti nyin melo? Ki gbogbo ẹnyin ara ile y'ara ranṣẹ sọ fun awọn ara oko wipe ko ṣe rọ ni ti Ṣabu ṣe ran'wo "ỌGA NI DUHATI" ti a npe ni **MESSRS: J. H. DOHERTY, Ltd.,** ti nwọn ṣeṣẹ ṣi ni rẹpẹtẹ s' ọna opopo nla Broad Street, l' ode Eko, nisisiyi.

Awọn ojulowo-aṣọ atata fun ọkunrin ati fun obinrin l' agba ati l' ọmọde lo pe'ju si Ṣabu na ṣiba; awọn ohun ọṣọ fun awon ọmọge-alafẹ nṣubu lu ara wọn; ṣọpọku-ọyọku si ni owo ọja wọn na fun tita.

Ki gbogbo ẹnyin enia y' ara lọ ra awọn ọpọ ọja to nṣe ojulowo l' ọdọ awọn ile iṣ' owo **Messrs: J. H. Doherty, Ltd** yi, nitoripe ko ṣe rọ ni gbogbo awọn ọja to mbẹ ninu Ṣabu titun yi jẹ.

Ẹnyin ero idalẹ le kọ'we pẹlu owo ṣ' ọwọ fun ọja ti ẹ ba fẹ ra lati inu ile-ọja:

**MESSRS: J. H. DOHERTY, LIMITED.**
*Broad Street, Lagos, Nigeria.*


[Awọn ẹnikẹni ti nwọn ba ti ipa ọdọ wa de ọdọ awọn Oniṣowo "Pambabari" yi, ki nwọn da orukọ iwe irohin "**AKEDE EKO.**"]

"WHERE IGNORANCE IS BLISS, 'TIS FOLLY TO BE WISE."

## OLOFINTOTO

—:o:—

### ONIWE IROHIN "AKEDE EKO" LO S'AJO!

Gẹgẹbi eto ikede fun irin ajo ti ẹnyin ọkawe wa yio ti ma ṣakiyesi ninu iwe irohin wa yi lati bi iwọn ọsẹ keji sẹhin, awa ni lati sọ fun gbogbo ẹnyin ọkawe wa na gbọ nisisiyi wipe Ọgbẹni Isaac B. Thomas, Olotu iwe irohin *Akede Eko* yi pẹlu iyawo *Editor* na ti nṣe alejo ni ilu Ijẹbu Ode ati yika awọn agbegbe ilu Ijẹbu Ode nisisiyi.

Ninu ọkọ elefin kekere l'ebute Idumagbo l'owurọ ọjọ Monday, ọsẹ yi, ọjọ 14, oṣu September yi, ni gbajumọ *Editor* na ati iyawo rẹ pelu omidan Abigail Oguniyi to nṣe akowe obinrin ni Office *Akede Eko* pẹlu William omọ-ọdọ *Editor* na jomọ wọ ọkọ de ebute ọja Ejinrin lati ibiti gbajumọ Ọgbẹni D. R. Otubuṣin ti ṣe ipese silẹ Moto-ka onigbadun to mu *Editor* na pẹlu awọn enia rẹ de igboro ilu Ijẹbu Ode.

Ninu iwe irohin wa yi l'ọsẹ to mbọ l'agbara Baba Ọrun ni *Editor* wa na yio bẹrẹ si kọ awọn "oyinkan" irohin aladun l'abẹ "Ero L'ọna" nipa awọn ohun gbogbo ti *Editor* na ba pade ninu "arẹwa" irin-ajo rẹ yi.

Ninu awọn ilu pataki l'ọna arọ 'ko igboro, Ijẹbu-Ode ti gbajumọ *Editor* wa na yio f'ẹsẹ rẹ ba fun ire itẹsiwaju iwe irohin wa *Akede Eko* yi ni awọn arọ'ko ilu bi:—Imushin, Iṣọnyin, Ijẹbu Igbo, Oke-Aga, Oke Agbo, Agọ, Oru, Ṣagamu, Ipẹru ati Odogbolu.

L'ọsan ọjọ Monday, ọtunla, l'agbara Edumare ni oniwe irohin na pẹlu awọn enia rẹ yio pada de si Eko.

Alọ 're o, abọ 're o, *Editor* tiwa ọwọn julọ!

### OMỌ TITUN ALEJO AIYE, ABỌ O!

Niwọn dede agogo mẹta-abọ ọsan koja iṣẹju diẹ ni ọjọ Friday ijeje, to nṣe ọjọ 11, oṣu September yi, ni a gbọ wipe Ẹlẹda fi ọmọbinrin kekere rubutu kan jinki gbajumọ ẹni rere Dokita ati Mrs. Henry Doherty; tayọtayọ ni awa fi ki baba-iya ati iya-iya ikoko tapẹ na, eyi ni bọkinni Ọlọla Dokita C. C. Adeniy Jones ati iyawo rẹ.

Ki Ọlọrun da ọmọde na si fun wa o!

### ỌLỌLA GOMINA CAMERON! MO NGBADUN RẸ.

Ni dede agogo mẹwa owurọ ọjọ Wednesday ti nṣe ọjọ 16 oṣu September, 1931, ni Ọlọla Gomina wa—Gomina Cameron—lọ bẹ Ọkọ Ogun ti a npe ni '*Daffodil*' wo, ni agbami. Bi o ti ṣe ninu ipo oye ati ọla rẹ ni Ọlọla Gomina fi lọ ṣe ibẹwo yi, a rọ agba lati inu ọkọ yi wa gẹgẹ bi ẹyẹ ati aṣa ti a gba pe ki a ṣe.

### TABI IBEJI NI WỌN KẸ?

O ta si wa l'eti fẹrẹn pe ni ọjọ Wednesday ti nṣe ọjọ 16 oṣu September, ni ọjọ ibi Ọgbẹni C. M. Silva, Amofin wa, to wa ni opopo Bamgboṣe Street, ni Eko, ati pe ọjọ kanna si ni ọjọ ibi Ọga awọn Ọlọpa Ọgbẹni T. I. Kester. Ki Ọlọrun ma ṣai fi ọpọlọpọ rẹ han wọn ninu ara lile ati ibalẹ aiya ni ile wọn. Amin.

### BRIMAH ARO ṢE BẸ O R'ỌRUN

Anu ṣe wa lati tu ọtọ Ọgbẹni Brimah Aro ẹniti gbogbo wa mọ bi Famuyiwa Aro On lo ti jẹ aṣaju fun awọn Ọmọ Ọba ti wọn ti do ti Prince Eṣugbayi Eleko lati bi ọdun melo yi wa.

A ko gbọ mpa aisan rẹ rara, anu si ṣe ni pupọ papa to jẹ ni asiko yi ti a ngbiyanju lati pari ija larin gbogbo awọn ọmọ ọba ni iku wa de ba.

Ki Ọlọrun ma ṣai pa aṣiṣe rẹ gbogbo rẹ.

### ỌLỌLA ERIC O MOORE

...gbọ pe alagba wa Ọlọla Eric O Moore, o dakan ...Ibadan fun ẹjọ Assizes ti o bẹrẹ l'ọhun ati ...o le pada wale titi ipari ọsẹ yi.

### IPADE ALAFIA (PEACE MEETING)

Inu wa dun pupọ nigbati awọn Ilu Committee nṣe ayan lati pari ija ti o ti wa larin awọn ọmọ Ọba ti Iga Idunganran. A gbọ pe wọn fi ipade yi si ọjọ ọsẹ ọjọ 13 oṣu September. Awọn enia to wa ni Ilu Committee jasi 51. Awọn ọmọ-ọba l'okunrin jasi 107, awọn ọmọ-ọba l'obinrin jẹ 166, awọn Ibiga jasi 40.

A gbọ pe awọn Ọgbẹni Brimah Aro, Sumọnu Faro, Adamọ Oniru ati Mimimi Ọlọkọ ko lọ si ipade na, bi o tilẹ ṣe pe a pe wọn, a bẹ wọn, a si rọ wọn to, ki wọn le wa si ipade na.

Ṣugbọn sibẹ a gbọ pe gbogbo awọn ti o pade ni ipade na lo fi ohun ṣọkan pe awọn ko fẹ ija mọ ati pe awọn yio wa ni irẹpọ lati igba na lọ; wọn pari ipade na niwọn agogo kan ọsan (1 p.m.) lẹhin na wọn fi ẹnu pa ukan wu-wu-wu ti awọn Ilu Committee pese silẹ; wọn tuka niwọn agogo mẹta ọsan (3 p.m.) Ki Ọlọrun ma ṣai jẹ ki irẹpọ le wa larin gbogbo wa.

---

THE ITINERARY OF THE PROPOSED TOUR OF:—

**Mr. Isaac B. Thomas,**

(EDITOR & PROPRIETOR OF AKEDE-EKO.)

IN IJEBU PROVINCE.

*Monday September 14th to 21st 1931.*

| | | |
|---|---|---|
| September | 14th | Leave Lagos and arrive Ijẹbu-Ode (Via Ejinrin) |
| " | 15th | At Ijẹbu Ode (Visit Imushin & Iṣọyin) |
| " | 16th | Proceed from Ijẹbu-Ode to Ijẹbu Igbo |
| " | 17th | At Ọjọwọ, Ijẹbu Igbo (Visit Oke Aga, Oke Agbo, &c) |
| " | 18th | Proceed from Ijẹbu Igbo to Agọ (Via Oru) |
| " | 19th | Leave Agọ for Ṣagamu, (Via Ijẹbu Ode & Odogbolu) |
| " | 20th | At Ṣagamu, (Visit Ipẹru, &c.) |
| " | 21st | Leave Ṣagamu and arrive Lagos, (Via Ikorodu.) |

NOTE:—The above Time-Table is subjected to alteration by the Editor if any unforseen circumstances compel him to do so.

---

## IN MEMORIAM.

In ever loving and affectionate remembrance of my dearly beloved mother
**COMFORT S. LEIGH**
Who departed this mortal life to join the company of the ransomed on the 26th day of September 1928.

"Sleep on beloved, sleep and take thy rest,
Lay down thy head upon thy Saviour's breast;
We loved thee well, but Jesus loved thee best,
Good-night! Good-night! Good-night."

*Requiescat in pace et lux perpetua luceat tibi.*

Her Son,

JAMES AYODELE ỌLATUNDE LEIGH

"BABALAWO A KU, ONIṢEGUN A RE ỌRUN, ADAHUNṢE KO NI GBE'LẸ"


ILANA ETO ẸGBẸ.

# Nigerian Mercantile Bank.

**Limited.**

**Head Office:**

LAGOS, NIGERIA.

TI A DA SILẸ NI NIGERIA NI ỌJỌ KỌKANDILOGUN, OṢU MAY, 1931.

## Awon Amona Egbe

The Hon. Dr. Dr. Curtis Crispin Adeniyi-Jones, M.B., CH.B., Pricilla Hall, Lagos.
*First Lagos Member of the Nigerian Legislative Council,*
*Chairman, Nigerian National Democratic Party,*
*Chairman of Directors, Nigerian Medicine Stores, Ltd.*

Winfried Tete-Ansa, Esq.,
*Life Fellow of the Empire Royal,*
*Director of Companies*
98, Broad Street, Lagos. Nigeria, and Castle Road, Christianborg, Accra, Gold Coast

Dr. Akinọla Maja, M.B., CH.B.,
*Director, Nigerian Medicine Stores, Ltd.*
*Director, Oshodi and Apena, Ltd,*
41, Layẹni Street, Lagos, Nigeria.

Joseph Mọdele Cole, Esq.,
*Contractor,* 25, Kopada Lane, Lagos, Nigeria

**Registered Offices:**
98, Broad Street, Lagos, Nigeria, West Africa, P.O. Box 553.

**Managing Director:**
Mr. W. Tete-Ansa, Director of Companies, 98, Broad Street, Lagos, Nigeria.

**Solicitor:**
Mr. W. Wells-Palmer, Barrister and Solicitor, Wilberforce House, Lagos, Nigeria.

**Secretary-Accountant:**
Mr. Dan. D. Quist, 162, Bamgbose Street, Lagos, Nigeria.

**Auditor:**
Mr. Hauzat Subair, Accountant, 10A, Bishop Street, Lagos, Nigeria.

IWE IFỌWỌSI KI ENIKẸNI TO LE WỌ ẸGBẸ IFOWOPAMỌ (BANK)

NIGERIAN MERCANTILE BANK LIMITED.

*(Ti a da silẹ ni Nigeria gẹgẹbi Ẹgbẹ)*

Iye Owo (Capital) ti a fi bẹrẹ Banki yi jẹ ẹgba-marun poun, (£10,000)

SI AWỌN OLOTU ẸGBẸ BANKI:—

**NIGERIAN MERCANTILE BANK LIMITED.**

Ẹnyin Bọkin /

98, Broad Street, Lagos Nigeria, P.O. Box 553

Mo san £ ........fun ọwọ......minu ipin ti oni sile marun-marun [5/-] fun ẹnikọkan ti a npe ni **Preferred Shares** ninu Banki yi, mo si torọ gafara pe ki e yọda iye owo na fun mi mo gba pa ng o gba iye na, tabi ti ko tile to iye na gẹgẹ bi Eto ati Ilana Ẹgbẹ nyin, mo si fun nyin li agbara lati fi orukọ mi sinu Iwe orukọ awọn Ọmọ Ẹgbẹ Ifowopamọ [illegible] iye ọwọ ti a yọda fun mi.

Bi emi ti jma kọ orukọ mi nigbagbogbo........................ Orukọ mi ni kikun. ........................

[Sọ bi Mr. Mrs. tabi Miss ni] Orukọ ibiti mo ngbe................. Iṣẹ ti mo nṣe...........

Ọjọ ti mo fi ọwọ sil iwe yi...............

**Akiyesi:**—Eniti nfẹ wọ Ẹgbẹ yi lefẹe elo bi o nfẹ [illegible] ajranjowo iyefọwo ti nkọ diẹdiẹ nigbamiran, a si le gba [illegible] owo-yowo

" Ẹ MAṢE JẸ KI ỌKAN NYIN BAJẸ: ẸNYIN GBA ỌLỌRUN GBỌ "

*Editor & Proprietor*:—
ISAAC B. THOMAS.

*Editorial Office*:—47, Bamgbọṣe Street, Lagos
P.O. Box No. 646,
Lagos, Nigeria.

**Telegraphic Address**
"KEDE-EKO" Lagos

*ORIN*:—" K'Olorun ṣọ wa k'a tun pade!
K'O i'iyẹ Kẹ dabobo wa!
K'O ma pese fun aini wa,
K'Ọlọrun ṣọ wa, ka tun pade.

K'a pade...... k'a pade!
K'a pade n'woyi o ẹ lo nibọ,
K'a pade ...... k'a pade!
K'Ọlọrun ṣọ wa ka tun pade.

# Akede Eko

EKO, SATURDAY, September 19, 1931.

## A W' AIYE MA NI IGBA, O DABI IGBA TI EṢINṢIN KU SI OJU ỌTI.

Igba l' asan ni olukuluku ọmọ enia ni ninu aiye, aiye ki isi ṣe ti ẹnikẹni ninu wa. Nitorina o yẹ pe ki olukuluku enia ma gbidanwo nigbagbogbo pe igba ti on ni ninu aiye ki on le lọ o ni rere, fun ire awọn enia ẹlẹgbẹ rẹ, ati fun ogo Ọlọrun pẹlu.

Ẹnikẹni ninu aiye yi ti o ba ṣe pe ogo ara rẹ nikan lo nwa, ti o ba ṣe pe ohun ti yio ṣ' anfani fun nikan lo nwa, ti o ba ṣe pe, ki ti on nikan ma dara ṣa lo nwa lai bikita ki ti awọn enia ẹlẹgbẹ rẹ bajẹ, igba aiye rẹ ko le ni-lari tobẹ, bi owọ rẹ ba si tẹ ohun ti o nlepa na, ki yio le gbadun rẹ rara.

Igba l' aiye. Bẹ gan a lo ri Ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn ti ku, ti a si nka wọn si enia nlanla, ki nṣe nitori nkan meji ni a fi nṣe iranti wọn bẹ, bikoṣe pe nitori ti nwọn lo igba aiye ti wọn, fun ire ilu wọn tabi fun ire awọn enia ẹlẹgbẹ wọn tabi fun Ogo Ọlọrun.

Owe awọn agba niyi pe " A w' aiye ma ni igba, o dabi igbati eṣinṣin ku si oju ọti," bẹ gan lo ri. Ẹnikẹni to wu ki o jẹ ti a bi s'inu aiye yi, ti o lo igba tirẹ ninu aiye na, ti o si ku lai ni nkan pataki kan ti o ṣe l'ọjọ aiye rẹ fun ire enia ẹlẹgbẹ rẹ, fun anfani awọn enia ilu rẹ tabi fun Ogo Ọlọrun, o kan wa si aiye lasan ni, iku rẹ ko si yatọ si ti eṣinṣin ti o ku si oju ọti.

Ko di igba ti enia ba ṣe nkan nla kan ti gbogbo aiye ma gburo rẹ ti a ma gb' okiki rẹ, ṣugbọn bi olukuluku yala ninu ile rẹ ni, yala ni adugbo ti o ngbe, yala ninu Ijọ tabi Janma to wa, ba le du u pe ki awọn enia wọnyi jẹ anfani igba aiye rẹ, nipa iwa rere rẹ, nipa iwa isore rẹ, nipa ibakẹdun rẹ, nipa ajo, rẹ, nipa iranlọwọ rẹ, ati nipa ajo kekeke miran ti yio mu inu didun, alafia, ati ifọkan-balẹ ba awọn enia ẹlẹgbẹ rẹ wọnyi, oluwarẹ k'ogo ja niyen, igba aiye iru ẹni bẹ yio si jẹ eyiti a o ma t'ọka si pẹlu ibukun, ti a o si ma fi ṣe apẹrẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu

Njẹ, ẹ jẹ ki olukuluku wa bi ara wa lere pe: ' lati ijọ ti mo ti mọ ara mi ni ẹda Ọlọrun kan l' ode aiye, kini ire tabi anfani ti mo ti ṣe ri, fun ire ilu mi, fun ire enia ẹlẹgbẹ mi ati fun Ogo Ọlọrun pẹlu?" Bi o ba ṣe pe a ri, ti a le t' ọka si, ẹ jẹ ki a mura giri ki a ma ṣe arẹ ninu rere ṣe, nitoripe awa o ka a ngb ti akoko ba de, ẹkun ibukun lati ọdọ Ọlọrun wa, ire ni awọn eina yio si ma su fun wa lọjọ aiye wa gbogbo.

Ṣugbọn bi a ko ba ri ohun ti a le tọka si pe, a fi ṣ'anfani fun ilu wa, fun awọn enia ẹlẹgbẹ wa ati fun Ogo Ọlọrun, nṣ ...bana—aw'aiye ma ni igba ni a jẹ ti o dabi oku eṣinṣin l'oju ọti.

Nitorina ẹ jẹ ki olukul ku wa du u lati lo igba aiye wa l'ọna ti yio mu anfani, ire ati ayọ wa ba awọn enia ẹlẹgbẹ wa, wa ba ilu wa ati fun Ogo Ọlọrun nigbana ... rọ'ri-ku ni, igbehin wa yio si ni ayọ, ao s' jẹ ẹni alabukun fun.

Ki Baba ma ṣai fun gbog o wa l'okun ko le ri bẹ fun wa.—Amin.

## IROHIN ERE AWỌN EGBE YOUNG STARS NI PỌTA

( *Lati ọwọ Kekere ...* )

Mo juba o,

Jọwọ dakun ba mi fi ... kekere yi si inu iwe irohin rẹ. Ki emi Kekere Eko to bẹrẹ si sọ fun awọn ... rẹ nipa labari ere ọjọ kejọ oṣu August ... Ma fi ẹnu paṣamọ niba jaba nipa ... awọn agbalagba to wa ni ilẹ yi, ni... emi Kekere Eko ka iwe irohin ti a np... ni *Lagos Daily News* pe Ọba wa Eṣugbayi ... pe ki kotu ti Nigeria tun gbọ ẹjọ rẹ. ... Kekere Eko ṣe iwe ipade si ile Olori ... ẹgbẹ Maiyegun (*Circular*) lati ro nip... ba... ni a o ti ṣe ariya na si. Awa p... lọ... wa pe, ki ẹni kọkan da ṣile me... Ṣugbọn owo ti a da yi, ti a ko ba ni ṣe ti ... lẹsọ a o ti to nkan bi pọnwun mejila ... Ninu owo yi nwọn ko ra adi... nwọn yio ra itan ẹran kan o. ... kan ta gbọ lẹnu wọn nipe ojo lo ba ... jẹ. Tẹ, ka tiẹ gba bẹ, Eyi tẹ ba awọn ọdọmọkunrin gotẹ si nkọ o? Bẹ lẹ sa ... da owo, sibẹ kọ awọn ọdọmọkunrin yi wọn tun na yin jẹ pẹlu alafia nyin tẹ jẹ ... nipa ti alafin tẹ jẹ awa yio bere lọwọ ... sẹ eyi yala bi alafin ti Ọyọ ni o bi ti Oṣugbo ni o, awa yio fẹ mọ ni ọjọ miran ọjọ re, Nipasẹ pe, awọn ọdọmọkunrin ko mọ bi owo ti nwọn da yi ti ṣe nrin lọ, mu ki ... ya ara wọn

## "ALL THE HOPE OF MAN IS IN THE MAN CHRIST JESUS."

lati da ere ti nwọn nṣe ni ọjọ Satide jẹ ijọ kẹjọ oṣu August, 1931, eyi ni nwọn ṣe iranti pe, o di ọdun mẹfa gbako ti nwọn mu olufẹ Ọba wa Eshugbayi kuro ni Idunganran. Ṣugbọn a fẹ lati sọ gbolohun kan to jẹ pe, oniwe irohin Pọta to pe re ni *Nigeria Observer* wi, ti o sọ pe, nwọn dupẹ lọwọ awọn bi Ọgbẹni Luke O. Thompson, J. M. Johnson bi *President* ati *Vice President*, a ko ba oniwe irohin yi wi, eni ti ọbẹ rẹ ba dun ni nwọn nko ẹkọ ti. Eyi ti oniwe irohin yi fi kuna ni a fi ha ọ ti aṣọ yin o, ni ọjọ ti a fi pade si ile Ọgbẹni Agbasi gbogbo awọn ti o pejọ lọjọ Sonde yi nwọn kan yan Ọgbẹni Agbasi ni Alaga ni. Eyi ti awọn Oyinbo npe ni *Chairman* o si da emi Kekere Eko loju pe, Ọgbẹni Luke O. Thompson tabi Ọgbẹni J. M. Johnson ko le bura pe, on ni *President* tabi *Vice President*. Bi o ba si jẹ, emi Kekere Eko lo purọ inu mi yio dun *Nigeria Observer* ba le sọ ẹni ti o fi nwọn jẹ oye aramu yi. Ati pe irufẹ awọn lo fi Luke O. Thompson ati J. M. Johnson jẹ irufẹ oye aramu yi? Loto awa mọ daju pe, Ọgbẹni wa J. M. Johnson je *President* awon ẹgbẹ kan ti nwọn njẹ Jolly Club, awọn ẹgbẹ yi lo fi J. M. Johnson je *President* ki ṣe ẹ lo fi jẹ *President* o. Gẹgẹ bi a si ti mọ ni ilẹ ti nipe awọn Agbalagba Pọta lo npe Luke O. Thompson ni Alafin. Ṣugbọn bi Alafin yi ba si duro ni iduro *President* awa ko mọ o. Ṣugbọn awa yio bere ni ọjọ miran ọjọ re itumọ oye ti Alafin yi. Bi ti Alafin Ọyọ ni o, bi ti Alafin ti Oṣugbo ni o, awa yio bere eyi nigba ti o ba ya. Ni ọjọ Satide ijọ kẹjọ oṣu August 1931 ni awọn Ẹgbẹ Youngstars ṣe ariya ribitibi kan ni ilu Pọta to ṣe rọ ni ere na jẹ, gbogbo wọn da aṣọ ti awọn Oyinbo npe ni sailor kọla. Fila Tamuṣanta ti o ni pupa lotun ati funfun osi ni nwọn lo. Bi o ti to dede ago mẹrin irọlẹ ni ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ yi pe jọ si ile petẹsi alaga wọn. Ọgbẹni Captain Martins ọmọ S. O. Kuleji, awọn ọmọ-ge meji kan, ti oruko won njẹ Taiwo Cole pẹlu Abẹbi Roberts nwọn ko ṣe rọ sẹhin. Nigbati awọn Ledi meji yi yọ lopopo ọna, bi emi Kekere Eko ko ba ni sọ aṣọ-dun awọn meji yi dabi Egbin. Awọn na ru si inu aṣọ Sailor ti wọn; o jẹ ki emi Kekere Eko ranti orin kan ti a ma nkọ ni Eko pe :—

> Ma ba ẹ dele
> Ma ba ẹ dele
> Bo ba ti le gb'emi larede
> Ma ba ẹ de'le ! ! !

Nigbati o di alẹ niwọn ago mẹjọ abọ awọn ọmọ Ẹgbẹ yi wa lọ fi abọ si ile Alaga wọn nibiti wọn gbe ti se aladun onjẹ silẹ fun wọn. Bi o ri o mọ iresi jẹ wa ba ọka riro pẹlu ọbẹ ewedu to jire nibẹ, bẹ si ni ọbẹ ẹja tutu tun pitu sibẹ ati ẹran ti wọn se ni furayi (Fry) a jẹ fi ẹhin ti ni onjẹ alẹ ọjọ na, ko si ikunsinu kan pe mo dawo emi ko ri onjẹ jẹ, dede, a fi ẹni to ba ma sẹ Oluwa lo ma sọ pe on ko jẹun. Emi Kekere Eko ti ki nṣe ara awọn ọmọ Ẹgbẹ yi, mo jẹ, mo mu, gbogbo ẹnu mi pẹlu lo nṣe yodo bi ẹnipe a jọ dawo ni, tobẹ ge onjẹ ati nkan mimu tun ku di ọjọ keji bi ẹru. Ni dede ago mẹsan abọ alẹ, awọn ẹgbẹ yi wa lọ pa agbo ere ijo si titi Agbasi, ijo wa sọlẹ ni pẹrẹwu awọn adelebọ to gbamuṣe, awọn ẹlẹyinju ẹge bi Mrs. Marsh, Mrs E. S. Onipede, Mrs. D. Ola Williams, Mrs. Odu. Thomas, Mrs. Jonah, Miss Kẹmi Taylor Mrs J. M. Johnson pẹlu awọn ọdọmọbirin ti a ko le daruko wọn tan. Emi Kekere Eko ṣakiyesi pe, ituje kan ko si larin awọn ẹgbẹ yi; ṣugbọn emi Kekere Eko sọ laisi ibẹru tabi ifoiya pe awọn agbalagba wa ko le fọwọ sọya bi awọn ọdọmọkunrin ti le fọwọ sọya pe wọn tẹ wa lọrun. Ni ọjọ Sọnde nigbati wọn lọ yọ Photo a tun ri ẹru to ku nilẹ. Ṣugbọn emi bere ni o, Adejumọ o, sisi kọ lo sọ pe o na ku? ẹnyin agbalagba o dọwọ yin ni Pọta o. Boya Ọba wa Sanni Owo ti ko si ni ile lo jọki nkan na ma rin tata. O ta si emi Kekere Eko leti firin pe awọn ẹgbẹ yi yio fi Photo nla kan ranṣẹ si Ọba wa Eshugbayi Eleko lati fi si inu Iga Idunganran (*that is full enlargement.*) Ewo ni awọn agbalagba yio fi ranṣẹ wa yi o? a si tun gbọ pe awọn Ẹgbẹ yi yio tun lọ ṣe ere ni ilu Aba. Ki emi Kekere Eko to pari ọrọ mi, emi ko le ṣai dupẹ lọwọ Bintu Ipayeh fun ayan to ṣe lọdọ awọn ọmọ Ẹgbẹ tirẹ, fun Bow to ba awọn Youngstars ta. A si tun ki Ọgbẹni wa Oyewọle, fun ayan to ṣe sidi Asiya ti awọn ọmọ Ẹgbẹ gbe jade lọjọ na.

Awọn agbalagba wa to ba wọn ṣe eyẹ lọdọ awọn Youngstars a ki wọn pupọ fun ifẹ ti wọn fi han lọjọ na, awọn Ọgbẹni bi C. Perriera, Ọgbẹni S. I. George, Ọgbẹni D. S. Morgan, Ọgbẹni T. E. Cole. Ọgbẹni E. S. Onipede, Ọgbẹni J. A. Mann, Ọgbẹni A. B. Abel, awọn Ọgbẹni wọayi si ba wọn jo kiri. Pọwun bi mejila a ko ri nkan ti wọn fi ṣe? Iwọ mọ? O ti o. To, bi gbogbo rẹ ti lọ si kọ yẹn? O di ọjọ miran ọjọ re o.

Editor Akede Eko abẹ ifari rẹ ko ni ku bọrọ o, ọko Ọba ko ni ṣa ọ lẹsẹ, abọ mi re o. Eyi ti mo ba ri ni Aba ma yin si nyin leti o.

Emi ni tirẹ nitotọ
KEKERE EKO.

"AJE GBE ỌMỌ SỌ'NU BI OKO."


# MOTỌ-KA-AYỌ KẸLẸ-ẸLẸ.




Ko ṣe:rọ ni Motọ-Ka-ẸLẸ ti aworan rẹ mbẹ l' oke iwe y..
Awọn ijoko ti nwọn ṣe sinu Motọ-ka na jẹ eyiti o rọ enia l' ọrun pupọ lati joko le.
Gbogbo awọn irin-iṣẹ ti nwọn fi ṣe Motọ-Ka na ni nwọn pi 've
Bi enia ba joko sinu Motọ-ka-ẸLẸ na bi igbati enia wa ninu iyara onigbadun ni.
Bi enia ba mbẹ ninu Motọ-ka na ti o ba si ngbe enia rin lọ l' ojuọna, oluwarẹ yio
"Ko-ṣe-rọ" ni awọn ojulowo Irin-iṣẹ-ape ti nwọn fi ṣe iṣẹ si Motọ-ka na l' ara.
Ẹ lọ bere tabi kẹ kọ iwe si awọn oyinbo onisowo-Motọ ti a npe ni :—

## THE UNITED AFRICA COMPANY LTD.

**MOTOR DEPARTMENT.**

**EBUTE METTA.**

**and at Abeokuta, Ibadan, Ijebu Ode, Benin City, Aba, Onitsha, Jos, Kano, Zaria**

**Phone E.B. 11** Telegraphic Address UNAMETTA. P.O. Box 7 Ebute Metta

"GIVE US THIS DAY OUR DAILY BREAD."

## The Life History of Me, Segilola, Endowed with fascinating eyes, the sweetheart of a thousand and one men.

CHAPTER 13

To THE EDITOR,
AKEDE EKO.

Dear Mr. Editor,

Last week, I promised to give an account of my preparation for our marriage and also to tell what happened between me and Olojo our medicine man.

I shall first relate what happened between me, Ayọka and Olojo, because it was a very painful matter to me whenever I remember it. But let no one expect that I will tell what happened between Ayọka my friend and the medicine man. I shall only relate what concerned me in the matter. There is no other one to be blamed first, but I Segilola, because I put myself in his way, and he took advantage over me, and he made use of this song at the time:—

I was sitting in my house,
It's your daughter who came to visit me
I was sitting in my house,
It's you daughter who desired the play.

Olojo was one of the medicine men in those days famous for their skill in medicine. He was living at Oke Popo near the compound of Durosinmi, and some of the elderly men now living must remember this medicine man called Olojo.

Any one who follows bad Company whether man or woman must see what is disagrerable to him or her. It was my waywardness which brought me accross this man.

My friend Ayọka made the suggestion to me that it would be a good thing, if both of us could get aim. If a Priest or a medicine man to be adopts making "Juju" for us so that we could be adopts in deceiving men to get money from them, whether now that we were maidens or after we should have been married.

One moonlight night both of us went to the house of the man, he was pleased to see us both. He enquired for the object of our visit. Ayọka told him that we came to consult Oracle about ourselves. He asked us whether he should consult for us both about the same thing or separately for each of us. We told him to consult for us separately, and he asked one of us to enter into his consulting room, and that the other should remain in the Piazza. My friend Ayọka was the first to enter and after about half an hour, he came out and I went in next. He told me to speak quietly over a three-penny piece, and after that to throw it into a white plate, which was in his hand, and what I said over the three-penny piece was about my preparation for marriage, how the matter between the man at Victoria Road would end and whether I would be happy as wife in Bankole's house. The man took up the plate, and examined the three-penny piece I threw in it; then he covered himself over it with the white clothe (I must not omit to state that there were two red-feathers of the polly in the white plate).

After about ten minutes the man uncovered himself and told me that I would be a famous woman, and that many men would be eager to marry me; that I should look well after myself, and that he was p r e p a r e d to do all sorts of medicines to safeguard me.

Thus I b e c a m e a frequanter of this man's house and he took from me many of the valuable clothes which I had received from the men who were my lovers and which I kept with Ayọka in their house and a good amount of money also.

It is truly said that "*He who owes God anything, it is to the devil he will pay it.*" So is the case between me and Olojo. Ever since I had been having dealings with men, none of them had ever seen my nakedness. But I regret to say that this medicine man called Olojo was the man who deprived me of my virginity.

My mother did not know any of these things and this secret was unknown to Banole with whom I was now preparing to marry according to the rites of the Church.

Next week, God's willing, I shall speak about my marriage. I thank you, dear Editor, for keeping my name still secret.

I am,

Yours very Sincerly

SẸGILỌLA ẸLẸYINJU ẸGẸ.

---


## ARA LILE NI OGUN ỌRỌ.

Orişirişi Egbogi Oyinbo ti o daju fun orişirişi arun bi ti aşẹ Dudu, Aşẹ Iilami, Ẹda, Ẹyọ, Iju, Oyi, Inarun, Jẹdijẹdi, Atọsi, (Ẹtẹjẹ, Ọlọyun, tabi Alabẹrẹ) Inuririn tabi kikun, Isọye, Ẹlọri, Otutu, Ipa, Ọrẹrẹ tabi oniruru arun ti o ndi obinrin ọwọ ninu ọna ibimọ ati Imarale ọkunrun ẹ le ri lọdọ wa. Kọwe si le wa bi o ko bawa.

ẸLẸNUMẸNUMỌ NI AŞIRI ỌDỌ WA.

A nta Jingi Ikawe, ati ohun elo irin-iṣẹ Fọto.

**OMI-ADE STORES,**

P. O. Box 783,
45, Bamgboşe Street Lagos.

*Branches at*:—45, Bamgboşe Street, Lagos,
35, Abẹokuta Street, E. B.
Ibẹrẹkodo Market,
Ikija, Abẹokuta.

"A ṢE ỌRAN IBAJẸ ṢEBI TON L'A NWI A ṢE BURUKU O KU ARA FU"

# NOTICE.

*(In the matter of the Estate of)*

**Samuel Ayoola Sodamola Tejuoso.**

*(Deceased)*

*Pursuant to the Statute 22nd & 23rd Victoria Chapter 35 intituled An Act to further amend the law of property and to relieve Trustees.*

NOTICE IS HEREBY GIVEN to all Creditors and other persons having any claims demands upon or against the estate of SAMUEL AYỌ-ỌLA ṢODAMỌLA TẸJUOṢO, Clerk, of 102 Tokunboh Street, Lagos, in the Colony of Nigeria (deceased) who died in the African Hospital, Lagos, on the first day of December 1929, intestate and whose letters of Administration of his estate were granted to me Akitoye Tẹjuoṣo Clerk of 33, Pike Street Lagos, and Plots 1 and 2 Block Yaba Estate the elder brother of the deceased in the Supreme Court of Nigeria on the 15th day of January 1931 the Administrator herein named are hereby required to send in writing particulars of their claims and demands to me on or before the 30th day of November, 1931.

And notice is hereby given that after that date I will proceed to pay and distribute the assets of the said deceased among the parties entitled there to having regard only to the claims for which I shall then have had notice and that I will not be liable for assets of the deceased or any part thereof so distributed to any person or persons of whose debts or demands I shall not then have had notice.

And all persons indebted to the estate or holding any effects of the deceased are hereby required forthwith to pay or deliver the same to me.

Dated at Lagos this 2nd day of September, 1931.

(*Sgd*) AKITOYE TẸJUOṢO.

*Administrator of the Estate*

## IROHIN OGBOMỌṢỌ

### OLE A GBE ỌMỌ ENIA BI ẸNI GBE EWURẸ

Ninn oṣu Ọgọsiti (August) ni okiki nkan gbai pe awọn gbọmọgbọmọ wọ ilu Ogbomọṣọ ati pe ọmọde kekere meji ti nu.

Eyi jẹ ki gbogbo ilu dide giri, Ọlọrun si ṣe, ọwọ tẹ ọkan ninu awọn gbọmọgbọmọ na, awọn ọlọmọ si ti gba ọmọ wọn pada.

Ki Ọlọrun Alanu fi iṣọ rere Rẹ ṣọ wa lode to ni.

### GBAJARE ! ILU LARE GBE O ! !

Ọrọ oke iwe yi lo bọ lẹnu wa ni irọlẹ ọjọ karun oṣu yi ti iṣe September 5 nigbati ariwo nla ta loju-de Ṣabu ọkunrin kan ti njẹ Akinwale, ẹniti gbogbo enia mọ bi Tutọ. Nigbati a sure de bẹ ti a si ... Balẹ ilu Ogbomọṣọ ti nbu ọkunrin na, ti a si ... ti gbogbo enia jẹri pe ọkunrin na ko ṣe ẹ beni ... ro o. Họwu ! mo ṣebi lailai ni ẹni to ja ni lo ... enia si ti ju enia ? A ha le binu ori ki a fi fila ... idi ?

Ilu lare ma ma gbe o !

MABINUORI.

### PAṢAN TI A FI NA IYALE, MBẸ NI PẸPẸ FUN IYAWO.

Akọwe kan lọna ilu oke, o ri okunrin kan ... nṣe iṣẹ labourer, o faju rẹ mọra, ọkunrin to nṣe labourer yi mọwe tata, Akọwe yi yọkuro nibi ... Cleaner, o ni ko ma ṣṣẹ lọdọ on bi Messenger warawere, o ti lọ ba ẹgbọn rẹ to jẹ ogunna gbogbo to ndatọ lẹnu igbin lọdọ Oyinbo agba, o nbẹ ẹgbọn rẹ Chief Clerk yi pe ko gba on, bi Cleaner yi ... ti ṣe di Clerk, Akọwe ẹgbọn rẹ ni, enia ma ... o fẹ ṣe ara rẹ ni igi abibo, maṣe dana si ara ni ... aburo Chief Clerk yi ni ko ri bẹ, ọmọrere ni okunrin yi, o tẹriba pupọ Chief Clerk ni, kiyesi, okunrin ... yio ṣe jamba fun ọ, o si kọ sinu iwe fun daju ... yio ri bi on ti pe yi.

Chief Clerk ṣe iwe de ọdọ Oyinbo agba, ... Oyinbo agba fọwọ si pe, ki Cleaner yi di Akọwe inu akọwe yi ndun pe ẹgbọn on ba on mura si ... na. Akọwe yi fi gbogbo iṣẹ han Cleaner yi. Lẹhin na ọkunrin yi wa lọ ṣe ilẹdi ọga rẹ lọdọ Oyinbo ... Oyinbo fi dojuṣọ ọga na, ọkunrin yi sọ fun Oyinbo pe on le ṣe gbogbo iṣẹ office, ṣe Oyinbo na ... on lo ṣe iṣẹ na, were Oyinbo ti gbija pẹlu ... yi lainidi, ti nwọn fi gbe kuro nibiti o ti ... ti nwọn si fi gbe lọ sọna Odo-Ọyọ. Ẹ o wa ri ... ti ṣoro ṣe si.

Makanmakan loya nkan, o si ya wa lẹnu pe ... bi oṣu meji sẹhin, akowe yi na gba (absent) ... iṣẹ na, o si nwa iṣẹ iṣọwo kiri.

A ko mọ rara pe on na le kuro nibiṣẹ na ... Ki olore pẹ, ki oṣika pẹ, ilẹ nikan lo mọ ẹniti ... tẹ on pẹ.—

### IYA ALATA KILỌ F'OMỌ RE

Ni akoko Centenary, ọrẹ wa kan ni on ... iyawo on lọ si Abẹokuta, nigbati o de, iyawo, ... iyawo ati gbogbo ile yọ ki ọrẹ wa na, o pẹ ... ọrẹ wa ni on nlọ si Ake, nigbati o ma pada, iyawo ... ti de Lafẹnwa, ọrẹ wa binu titi o ni loto ... loju lasan, nigbati iyawo de, ọkọ bere, o ni on ... sọdọ ẹniti o nba on tọju ile, ọkọ mu suru, o ... ṣe diẹ ọkọ nri on pẹlu ẹniti o wa lọ si Lafẹnwa, o bere pe tani baba Adini yi ? iyawo ni on ... aburo rẹ obinrin ni ọrẹ, ṣugbọn aburo na si ti ... ọkọ ni o dara, lẹhinti iyawo pẹlu ọkọ pada wa si Eko, ọkọ tun nri orişirişi iwe lati ọdọ ẹniti obinrin pe ni ẹgbọn ọrẹ on yi, ẹnu ya ọkọ na, ẹri ... ko jẹki iyawo yi simi, o wa nsọ kiri pe ọkọ ... lagbaja ọrẹ on, bi iyawo ba gbe ọsẹ meji lọdọ ... a ni on nlọ si ile, ninu ko sọ pe on nlọ ṣe ... nile tabi ko ni enia kan ku.

Lọjọ na, a ri iwe mẹta gba lọwọ ẹgbọn ọrẹ iyawo yi, bi o ba si woye diẹ ti iyawo ko ba ... na a rọ sinu Motor, nigbamiran ti ọkọ iyawo ba ti kuro, on na a si wọle, a ... ma ba iyawo jiroro bi owo na ti ma ri. Ẹ ... bi awọn obinrin wa ti nṣe aidara fun ọkunrin ... Obinrin yi fi gbogbo odo lọ lyere si, nipa bayi, Oluwa ko le gbọ adura rẹ. Oluwa lo nṣ'ọmọ.

EBIO-MỌ.

# PIRELLI

## THE WORLD'S BEST

THE TYRE

To Suit all Roads and all Conditions.

***Guaranteed never to let you down.***

Obtainable at the Sole Distributing Agents:—

## S. C. I. N.

37, MARINA, LAGOS.

**And at all Branches throughout Nigeria.**

## EUROPEAN RECORDS

!NEWLY ARRIVED!

**AT REDUCED PRICES**

**Full Stock of Records of our**

INTERNATIONAL CATALOGUE

Damnation of Faust
In a Persian Market
From Opera to Opera
The Blue Danube
Il Trivatore /Rigoletto
Marienklaenge/ Kaiser Waltz ( Strauss )
Ave Maria ( Schubert )

Down in the South
Laughing Records

**Obtainable at our**

## NIGERIAN RECORDS

WILL ARRIVE

**Full Stock of Records of our**

NIGERIAN CATALOGUE

! Sakara—Rara—Samba !

Yoruba—Litani and Church Songs

Arabic Prayers and Koran-Lectures

Abibu Abibus—Saka Jẹjẹ—I. Dẹnge

Ajapẹ Ilọrin—Mọmọdu Kokoro

**Obtainable within the next day at our**

Gramophone Shop "ODEON"

## WITT & BUSCH.

# OGUN MẸNTỌLETỌMU,—AWO-'GBA ARUN.

Egbogi Mẹntọletọmu A-j ẹ-bi-idan. Ki ẹnikẹni maşe şaiI ma ni ogun atata ni l'ọwọ ni ile fun lilo nigbakugba.

## Mentholatum
## Cures Colds, Chills & Fevers.



STOP Colds, Chills and Fevers at once lest they lead to Serious Trouble—MENTHOLATUM is the finest remedy.

For COLDS IN THE HEAD apply MENTHOLATUM to the nostrils and breathe the antiseptic vapours. The Cold is checked at once and the COOLING, SOOTHING action relieves all soreness. For CHEST COLDS rub well all over the Chest.

For FEVERS rub MENTHOLATUM all over the body, relief is quick and permanent and it cools the skin and stops the aching pains.

*Sold everywhere in West Africa.*

TRADE MARK
**MENTHOLATUM**
REGISTERED

THE MENTHOLATUM COMPANY, LTD., SLOUGH, ENGLAND.
*Over 20 million pots sold last year.*

Ojulowo ogun bi Mentọletọmu ş'owọn pupọ yika gbogbo aiye, ki gbogbo enia ma ni Mentọletọmu ọwọ ni i nigbagbogbo nitoripe Ẹkun baba ọdẹ si egbogi na ni fun gbogbo awọn arun ara.

O ju ẹgbẹrin o le adọta-ọkẹ igo egbogi ti a npe ni MẸNTỌLETỌMU ... ti a nta l'ọdọdun kakiri gbogbo agbaiye, ni gbogbo ilẹ Iwọ-orun Afrika li a si mọ bi egbogi na ... to.

Egbogi ti a npe ni MẸNTỌLETỌMU yi ni egbogi totọ fun wiwo ... gbo arun ti nba Awọ ja, Ori-fifọ, Otutu-ori, Ara-jijona, Ọgbẹ ati Apa-ọgbẹ.

Gbogbo awọn Dokita ni ilu gbogbo li o nrohin pe egbogi na ni lilo fun t'agba ... t'ọmode.

Ri i pe ojulowo MẸNTỌLETỌMU yi ni o ni l'ọwọ ki o ma si şe jẹk... a ta aiyederu ... nu o.

Printed at "Tika-Tore" Press, 20, Market Street, Lagos and Published by ISAAC B. THOMAS, at 47, Bamgbose Street Lagos